# EKO AKETE.

"EMI YIO FI OHUN TI O NDUN MAKUNNU HAN AWON ALAGBARA, NGO SI JE ALAGBAWI AWON ODI."—W. T. STEAD

VOL. III. No. 148 SATURDAY, MAY 16, 1925. 4d

**Declared Circulation 1,600 Copies Weekly.**

**White's Golden Female Tonic.**

A splendid Remedy for female diseases such as:—Barrenness, Weakness, Painful and Irregular Menstruation, Leucorrhœa (White's), Cramps Ovarian, Neuralgia, Inflammation of the Ovaries. A tendency to Miscarriage etc., etc.

**Price 10s. per Bottle.**

**Made and sold only by** VICTOR WHITE, ESQ
41, Offin Road, Lagos.
*N.B. Not obtainable elsewhere.*

N. V. HANDLEMATTSCHAPPIJ V.H.
OYINBO **J. F. SICK**
Ọba Ilẹkẹ, Ile Ilẹkẹ, 9, Ita 'Bode lailai, Eko.

A jẹ Ajirera ninu òwò Ilẹkẹ, orișirisi Ilẹkẹ wọnyi wa ni tita :—

Ilẹkẹ Oyinbo, Ilẹkẹ Rubber, Ilẹkẹ Olomi Wajì, Ilẹkẹ Onikẹkẹ, Ilẹkẹ Elejo, Ilẹkẹ Ayinrin, Ilẹkẹ Oniwörò ati Fadaka, Ilẹkẹ Kerewu, Ilẹkẹ Jòjò, Ilẹkẹ Ōlokuta, Ilẹkẹ Oloruka, Ilẹkẹ Ẹlẹranko, Ilẹkẹ Didan Yinrinyinrin, Ilẹkẹ Meremere, Ilẹkẹ Mọjọkun, Ilẹkẹ Adumādan.

Ẹ wa wo Ile ọja wa ; A ni nkan wọnyi fun tita :—

Ikoko Taba Onigi, Jigi, Așọ Aran, Ẹrọ Agbado, Ife, Ọti Elewuro (*Beer*) ati Eleso Ajàrà (*Wine*), Awọn Onjẹ Ipanu, Așọ Iș'ọșọ, Ẹrọ Ere Ọmọde, Ohun Ọșọ, Abẹlà (*Candles*) ati ẹgbagbeje ọja miran.

A nta Mașini *Vesta*, a si ni *Cement* atata ti Portland ati Irin pipọn abẹ oni *Diamond*. Idi òwò wa wa ni Rotterdam, a si ni Ile Owo ni :—Calabar, Gablonz (Czecko-Slovakia) Gold Coast, Accra, Lome Hamburg, London, Venice (Italy).

# LEVER STORES LTD.

## THE PEOPLE'S STORE.

ALWAYS

## Something New

AT

## LEVER STORE

AT THE

***POPULAR PRICES***

## 3d. 6d. 9d. & 1s.

*Editor & Proprietor* :—
ADEOYE DENIGA,
*Offices*: 22 & 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

:o:

O KAN AGBAGBA, O KAN ARẸ.

Awọn Oyinbo Onișẹ Ọba meji l'a gbọ pe nwọn ku nibi iṣẹ wọn, ni Ọgba Iṣẹ Ilu (*P.W.D.*) ti ibi, lẹnu ọsẹ ti o kọja: Ijọba si ti kede pe arun onjini-ọjọ (*yellow fever*) nbẹ nilẹ yi. Ki Baba maṣai dawọ, oni arun, ọla arun, yi duro. Aṣẹ.

Ẹ KU ASIN PADA

Ọgọrọ enia ni Funfun ni Dudu lo sin Gomina Agba pẹlu iyawo rẹ ni *Friday* ọsẹ to kọja, nigbati o ṣikọ lọ si ilu rẹ patapata.

GOMINA AKURU YẸ'JO, Ẹ KU 'LEDE.

Bi agogo mẹrin ọsan ti kọja diẹ ni ọjọ *Friday* to kọja bẹni Adajọ-agba fi F. M. Baddeley Sẹkitẹri pataki Ijọba "jiyọ" nipa fifi bura nigbati a fi jẹ Adele Gomina agba to lọ lọjọ kanna; ni Igbangan Ile Igbimọ Aṣofin ti Ijọba la gbe ṣe "awo" na loju pupọ enia; awọn Ẹgbẹ-alaṣọ-ododo (*Soldiers*) dabira nipa iṣẹ ti ọga nwọn pe fun wọn ati nipa fere ti nwọn fọn pẹlu.

SUBUHANALAI!

KILARI YI, HABA? ILU, Ẹ GBERA NI'LẸ Ẹ DIDE, AFARA NIJA ẸKUN.

Gbukẹ la gbọ ni *Tuesday* ọsẹ yi pe Ijọba npete lati da awọn Oloye wa Onifila-funfun duro, afi Ọbanikoro nikan lo ma ku; lọgan ti a gbọ ọrọ abami yi ni a lọ wa idi rẹ bi irọ ti awọn kan nma sába lati tu tabi elubọ fun enia ni; nigbati a si wa'di rẹ, a ri pe otitọ gan ni. Ohun ti a gbọ pe o mu ọrọ bẹ wa ni ti abuku ti Ijọba sọ pe awọn Oloye na ta fun Aṣoju Ọba King Gomina Clifford nipa sisin ti nwọn ko wa sin i, nigbati o fi ibi silẹ patapata ni *Friday* ọsẹ to kọja, ti o jẹ pe Ọbanikoro Oloye nikanṣoṣo ni Ijọba wipe awọn ri ninu awọn ẹgbẹ rẹ to ku, ti a si sọ pe nwọn jẹ ọhẹn lati lọ sin Gomina Aṣoju Ọba King na, ninu ipade kan ti a gbọ pe gbogbo awọn Oloye Onifila-funfun na ṣe pẹlu Balẹ Ilu (*The Resident of the Colony*) ṣiwaju ọjọ ti Gomina na w'ọkọ, ṣugbọn ti o di ọjọ na tan, to jẹ pe kosi ọkankan ninu awọn baba wa na ki o yọ'ju l'Ebute, afi Oloye Ọbanikoro.

Dida duro ni pe Ijọba wipe awọn ki yio tun mọ wọn mọ́ bi Oloye, ati pe gbogbo ọlá ati ipò wọn bi Oloye Ilu Eko yio jẹ ohun ti awọn ko ni kasi mọ (*A withdrawal of Official recognition from all the White-Cap Chiefs of Lagos, but one*). Ọran fẹrẹmọfẹrẹmọ leyi: ẹnyin Agbagba Ilu ẹ jẹ ki a mura ki a san ṣokoto giri, lati lọ bẹbẹ awọn Baba wa wọnyi lai fi ọran na fa'lẹ. A ki fi Ejo tabi Ina sori orule sun. Afara t'on t'ewu lo nrin.

EYI HA TI JẸ O?

Ihin kan ni lati Ilaro nipa igba-ku-igba ti awọn Agbowode ngba owo ori nibẹ. A gbọ pe bi awọn enia ba wa lati nọja lati Ilu Okere ati Ileto miran, ni-ṣaṣa di-di ni a sọ pe awọn agbowode yi ma ra wọn mu lati gbā, lai bere lọwọ wọn bi nwọn ti sanwo bẹ ri ni agbegbe wọn. A ti lẹ sọ pe bi ẹnikan ṣe ṣi wọ si ọdọ ẹnikeji rẹ lalẹ ni Ilu Ilaro yi agbowode ni o ma ji irufẹ alejo bẹ lori ẹni ibi ti o gbe sun si ni ijọ keji lati gba owo ori lọwọ rẹ. Irufẹ iwa yi ni a sọ pe o ntu ọja ọrọrun ti nwọn nna nibẹ ka. Inu wa yio si dun bi Oyinbo Alabojuto ibẹ (D.O.) ba le ba ni wa idi iwa inira yi fun atunṣe.

[ *Copyright* ]

## "EKO AKETE" LAW REPORT.

[ Lati ọwọ ATOLUGBOKUN. ]

Ni ijọ kẹrin oṣu yi ni ẹjọ ganran ti awọn ọdaran bẹrẹ niwaju Ọlọla Ralph Molyneux Combe. Gbogbo ẹjọ to wa ninu iwe awọn arufin, (*Calendar of Prisoners*) jẹ meje.

Ekini :—Bogobiri ẹniti ijọba mu fun ẹsun ọsọlẹ ẹjọ yi ti wa lati oṣu *February* (*adjourned from February Assizes*)

Ekeji :—*Frank Robert Stephen Jameison. On or about the 29th day of November, 1924, at Lagos, with intent to compel one Pauline Judd to do an act which she was lawfully entitled to abstain from doing, to wit to leave her husband Frederick Judd and live with him the said Frank Robert Stephen Jameson, threatened the said Pauline Judd with injury to her reputation or to that of her said husband. c.c. sec. 366.*

Ẹkẹta :— (1) SAM SAYE (2) WITNESS WORES (3) OSENI AJOSE

*On or about the 12th day of November 1924, at Lagos. (1) Stole from a lighter fifteen bags of Cocoa the property of Messrs Elder Dempster & Company c.c. sec 390 (4) (c).*

*(2) Conspired with each other to steal fifteen bag of Cocoa the property Messrs Elder Dempster &s Company. c.c. sec 516.*

Ẹkẹrin:—Tom Ogbada *In the night of the 18th day of April, 1925, at Apapa broke and entered the dwelling house of one Mary Accra with intent to steal therein and did steal therein a sewing machine and basket containing various articles of the total value of £7. 10. 0. the property of said Mary Accra c.c. sec 390 (4) (c)*

Ẹkarun :—Hippolyto Akapo. *On or about the 8th day of September, 1924 at Lagos, broke and entered the dwelling house of one Ramotu Handu with intent to steal therein and did steal therein money, gold trinkets and beads of the total value of about £360. the property of the said Ramotu Handu. c.c. sec 411 and sec 390 (4) (b)*

Ẹkẹfa :—Osunmonu Zaria. *On or about the 12th day of April, 1925, at Ebute Metta stole a piece of cloth value 11/3d. the property of one Sadatu c.c. sec 390.*

Ekeje : –Frederick Alexander Davies. Gbogbo awọn ẹjọ na towa niwaju Adajọ agba la ka fun nyin yi. Ẹjọ kẹrin gẹgẹ bi a ti to ni ti ọdaran ti orukọ rẹ njẹ Tom Ogbada ẹniti o ni on ko jẹbi ṣugbọn nigbati nwọn wa di ọrọ rẹ. Adajọ ri pe o jẹbi o si dajọ fun wipe ko lọ si ẹwọn ọdun ka pẹlu iṣẹ asegan.

Ẹjọ kẹfa niti Osunmonu Zaria ẹniti o ni on k jẹbi lẹhin ti ijọba wa di ọrọ na tan Adajọ pala aro ẹpa, o ni wara nṣẹṣa lọ si ẹwọn ọdun kan.

Ẹjọ keje :—Ati ri iwe ẹsun rẹ ṣugbọn ni irohi wa ọsẹ to nbọ gẹgẹ bi o ba ti ri ẹ ma gbọ, ati ẹ mẹrin yo ku ti a ko ti sọ fun yin gẹgẹ bi Adajọ t da si.

Ni ijọ *Monday* ijọ kọkanla oṣu yi ni Adajọ Tew lọ si Kano lati la gbọ ẹjọ ti ọhun—ko to lọ o wa si Kotu ni arọ lati wa sọ ailera ti Adajọ Agba t ko le wa si ile ẹjọ, bakanna ni ọjọ *Tuesday* ij kejila oṣu yi ko si ile ẹjọ ganran tọtun tosi.

Ni ijọ *Monday* ijọ kokanla oṣu yi na irohin kan ni pe Lọya Adekunle Wright da kan lọ si Ibadan *Motor* lo mu lọ on pẹlu Akọwe rẹ Agba (tabi A.D.C.) lati la ṣe iduro fun ẹlẹjọ rẹ kan ti ẹjọ rẹ nbọ ni *Assize* Ibadan ti ọjọ kẹrindilọgbọn oṣu yi ijọ kan na ni Lọya Adekunle Wright pada bọ wa si Eko lẹhin to yanju nkan to ba lọ—Ara Ijẹun ẹ ka bọ o.

### "ẸHIN RE O, ẸHIN, Ẹ WA WOKU ỌLỌMỌ"

Ni ijọ *Sunday* ijọ kẹwa oṣu yi ni awọn ọmọ oloku ṣe ijọ mẹjọ oku Iya wọn Salimọtu Ebo ẹniti o fi ilẹ bora ni ijọ *Saturday* ijọ keji oṣu yi. Iya to ku yi on lo bi Ashiata Adukẹ ti ita 68 Evans ni Okepopo. Ni ijọ *Sunday* yi ti wọn ṣe ijọ mẹjọ Oku Iya na a ko le fi ẹnu rohin inawo ọjọ na ani lati ki Alhaj Atobajẹun, Ọgbẹni Y. L. Iginla, Ọkọ Ashiata Adukẹ, Iyafin Barikisu Abẹbi ati Sẹlia Ajikẹ, nwọn ku inawo, ọmọ a ṣe bẹ fun wọn. Ẹhin Iya a dara.

### NKAN NFẸ ṢẸNU RE NI ARẸMỌ, IBADAN.

Irohin kan ni pe Adukẹ Wright to wa ni ọdọ Anti rẹ Mrs. Okuṣẹinde ni Arẹmọ, Ibadan fẹ ṣe igbeyawo ni ijọ Alamisi ijọ kejidilọgbọn oṣu yi ni Ibadan. Ẹnyin ẹbi Wright, ẹ ku ipamọ, Ọlọrun ko mọjọ ro.

### "AGBO MEJI KO LE MUMI L'AKOTO"

Ni nkan agogo mọkanla ni ẹgbẹ *Printing Office* ni Eko ni *Motor* 592 nti ọna Joseph Street, bọ lati yọ si *Broad Street Motor* 559 nti *Broad Street*, lọna ọdan o fẹ kọja larin gbogbo enia gbọ wọn-ngaga ti *Motor* 592 to ko agba Simẹnti ru dologbe, *Motor* 559 papa o ba mi, ko dun mi ko jẹ ẹniti ko ba ; ṣugbọn Mọdigadi di ero ọrun a dupẹ lọwọ Ọlọrun wipe ẹnikan ko fi ara pá. Ṣugbọn bi awọn Ijọba ba le fi Ọlọpa kan sibẹ ko ma na ọwọ fun *Motor* yo dara nitori orita mẹrin nibẹ jẹ.

## This, That, and The Other

*By an Old Crow.*

### Up Again !

*"But fiercely ran the Current*
*Swollen high by mouths of rain*
*And oft they thought him sinking*
*But still again he rose."*

*—Lord Macaulay.*

*The Old Crow*, after all, is still breathing. Some unexpected problem had created itself and, thank God, has solved itself automatically, giving me back my usual leisure to get up my contributions for *Eko Akete*. Do you ask for my health ? I am 100 per cent strong and as happy as the lark.

I learnt during the brief intermittence that one Sinlo of *Eleti-Ọfẹ* and one *Hunter* of the *Nigerian Spectator* were both sick of acute pneumonia over a contribution of mine. Poor fellows—let us wish them a speedy recovery.

AN OLD CROW.


A HIGH SCHOOL

**"The Lagos Academy"**

Is recently established at 34, Pike Street, Lagos, by the REV. J. A. LEIGH, M.A., in which all ordinary subjects are taught including Algebra, Geometry, Latin and Greek, etc.

*For Prospectus of same apply to the*

REV. J. A. LEIGH

*Principal.*

Boarders are admitted by special arrangement and private students given instructions on different subjects for different Examinations at moderate charges.

ẸNIKEJI,

Agọ oke to yanju mbẹ lọdọ Iya Afin Saamọta Ikẹ Ọlọrun fun tita, ọpọku ọyọku ni owo wọn, lọ bere ni 3, St. John *Street*, l'Eko, leti ile Johnson Agbẹjọro.


No. 12, Fakolujo Street
Lagos,

The Editor,
EKO AKETE,
22 & 24, Williams Street,
Lagos.

Sir,

Have you any reason or reasons to give me as motive or motives for your Editorial of last Saturday in which you highly stigmatised the *Lagos Weekly Record* for its special edition of the 2nd of May 1925.

I observe that you have attempted to discourage a mass of readers of the *Record* and charge also the *Record* and other Leaders for being responsible for the present Eleko position and that some people are making a trade of the readers.

While waiting for your explanations, I have reasons to disclose the facts that you have made a sudden shift.

What were your own comments over the issue of the *Lagos Weekly Record* of the 20th January, 1923, and what was your own Editorial on the refusal by Government of the Monster Petition at the time.

Did you mean to make a trade of readers when you placarded Notices calling upon people to book for special issues of your paper in connection with the Mohammedan Case.

Did you send any part of the proceeds of the sale of that Special Edition to the Seriki of the Muslims, or to the Secretary of the Jamat or to the Imam Ligali.

It is a common knowledge that there are two different camps in Lagos with two different opinions to the House of Docemo. One camp to which the Editor of the *Lagos Weekly Record* and his Associates belonged was the one clamouring for years that Government should extend better treatment to the community and its Prince, the other camp was one opposing continually the interests of the community and its Prince.

To what camp did you belong ?

You ought to know that majority of people bought your papers for the purpose of enjoying *Alari-Ajanaku*, his well-arranged Yoruba and English phrases, and also of course. your Editorial in decent Yoruba terms when fighting the cause of the community and its Prince, but chiefly for the articles by *Alari-Ajanaku* and *Akirimanu*.

Shorn of those correspondents, *Eko Akete* is useless

What sort of assistance have you rendered yourself financially or otherwise to the Prince Eleko.

In what way were the *Lagos Weekly Record* and its correspondents responsible for the present Eleko position ?.

What label do you attach to the opposers ?

Yours faithfully,

J. A. FAKOLUJỌ.

[ Mr. Fakolujọ's letter as published above distinctly betrays the spirit of a man who is opposed to one's honest opinion expressed in print with regard to a matter, particularly if such opinion does run counter to his preconceived notion and bigoted views, which perhaps our friend holds dear, rightly or wrongly.

How, in the name of Heaven, can anyone satisfactorily explain to men of Mr. Fakolujo's stamp any momentous questions, such as the one which has since become the talk in town, and which has made Mr. Fakolujo pour the vials of his wrath on our innocent head ?

To continue argument or elucidation with such men is *like administering medicine to the dead.* ]

Ed.—E. A.

## IROHIN IKORODU.

"OHUN RERE HA LE TI NAZARETH JADE WA, WA WO!"

Ọrọ yi lo sọ si mi lọkan nigbati mo ri nkan ribiribi ti awọn ọmọ ẹgbẹ kan ni Ijọ *Wesleyan* ṣe. Eyi ti orukọ Ẹgbẹ wọn njẹ "IFẸTAYỌ BOYS" pe, ohun rere kan ha le ti Ikorodu jade wa, ohun na si dahun wipe, wawo!

Ni ijọ kẹrinla oṣu *April* yi (*14th April, 1925*) ni awọn ẹgbẹ yi ṣe Ajọdun kinni (*first Anniversary*) ti ẹgbẹ wọn, eleru sungi ni ọjọ na, ni Ile Ọlọrun ti *Wesleyan*, awọn ogunna gbongbo meji yi ni o ba wọn sọrọ lori Ifẹ gẹgẹ bi orukọ wọn. Awọn ni Messrs. F. O. Amọjọ ati Jacob Taiwo. Nwọn fi han awọn ọmọ ẹgbẹ wọn gbangba, gẹgẹ bi ifẹ ti dabi alupa ti a tan si arin okunkun, ti o nfi imọlẹ fun gbogbo enia, ti ma fa enia mọra lati ọna jinjin wa, ati nitorina nwọn si sọ fun wọn pe ki wọn jẹ ki iwa wọn ko fa enia mọra, ki wọn si ma rin pọ ni ifẹ (*love*). Lẹhin ọrọ yi ni Alabojuto ijọ yi gun ori aga iwasu rẹ, o si yan ọrọ iyanju rẹ ninu Iwe Orin Dafidi 133. 1.

Nibẹ lo fi han wọn boti dara lati ma wa nigbagbogbo ni irẹpọ (*unity*) ninu eyi lo tun fi apẹrẹ Jesu han wọn bi o ti jẹ pe Jesu fẹran lati ma lọ si Betani ni ile Mary arabinrin Lasaru, ati ohun pataki ti o mu lati ma lọ sibẹ ni awọn nkan mẹta wọnyi Ifẹ, Irẹpọ ati Alafia (*love, unity and peace*) o si kọ wọn lati ma wa ni irẹpọ, ifẹ, ati alafia, ki Ọlọrun ba le ma wa si arin wọn.

Inu awọn ọmọ ẹgbẹ yi si dun to bẹgẹ, to fi dabi ẹnipe ki Alabojuto ijọ yi ma pa ẹnu mọ.

Adura mi ni pe ki Ọlọrun le da ẹmi Alabojuto na si fun iṣẹ rere rẹ larin Ijọ *Wesleyan* Ikorodu ati larin ilu pẹlu, a si ba awọn ọmọ ẹgbẹ yi yọ fun Ajọdun wọn kinni, ki Ọlọrun ki o ma ba awọn ẹgbẹ na pejọ ninu ero wọn, ki o si jẹ ki ẹsẹ ẹgbẹ yi mulẹ. *Amin.*

Inu mi yio dun pupọ bi nba tun ri awọn ẹgbẹ miran lati rohin rẹ sinu iwe bayi, awọn ti nwọn yio tẹle apẹrẹ rere, ti Oluwa wa.

### THANKS FOR SYMPATHY.

Mr. and Mrs. D. O. Dosunmu on behalf of themselves and family hereby beg to return thanks to those who by personal calls, letters, telegrams, etc, have sympathized with them in the recent bereavement by the irreparable loss caused by the death of their beloved daughter MABEL LAYINKA OKE WILLIAMS (Princess Dosunmu) which took place on Wednesday the 29th April, 1925.

In affectionate remembrance of our dear son.

**Eric Olakunle White.**

Who departed this life on Monday the 12th May, 1925.

"Sleep on, dear Kunle, sleep, and take thy rest,
Lay down thy head upon thy Saviour's breast;
We love thee well, but Jesus loves thee best—
Good night! Good night! Good night!

FATHER AND MOTHER.

The West African Soap Co. Limited
APAPA, NIGERIA

*Manufacturers of*

**NEPTUNE**
PALE SOAP

**BUGLE**
PALE SOAP

**MAGNET**
CARBOLIC SOAP

will send Price Lists and terms to merchants upon application to

P.O. Box 522
Lagos
Nigeria

F 393

## NOW READY.

THE LIFE OF HERBERT MACAULAY, C.E.,

BY

ATARI-AJANAKU

in English and Yoruba, price 2/- Obtainable at the "EKO AKETE" Offices and from B. Farawe Davies, Dosunmu Street, Lagos.

Iwe Igbesi-aiye Habati Makọli, şile meji-meji. Atari-Ajanaku ọkọnrin na ni o şe e!


---

Iwe yi kun fun itan Makọli lati kekere, lati ọjọ ti iya rẹ ti fi ori rẹ sọ'lẹ l'aiye, titi o fi di ẹni ọgọta ọdun li eşi. Ọrọ nipasẹ ilẹ wa wa nibẹ pẹlu, ati wahala ti Makọli şe nipasẹ rẹ; ọrọ nipasẹ Eleko wa nibẹ pẹlu, ati aworan Makọli, pẹlu aworan (*Photo*) nigbati Ọba Gẹsi (*King Georg V*) ngb'ọwọ lọwọ Oloye Oluwa ni Ilu Oyinbo, ti Makọli si gbe Ọpa Eleko dani, Ọpa ti o di iyọrọ ti o ho t'olori t'elesi wọn.

A fẹrẹ le wipe aworan wonyi nikan ti o wa ninu Iwe yi to şile meji lọtọ, lai ka igbadun ọrọ nla ti o wa ninu Iwe na papa. Lati ta Iwe na ni şile meji-meji dabi igbati enia kuku fi şe sara, nitoripe ko kaju inawo ti o wa lori rẹ. Nitorina, o yẹ ki iye enia ti o le ri Iwa na ra ki o to tan tete sure lọ ra. Iwe "ọmọ ni yio j'ogun" ni, a si tẹ ẹ ni ede Gẹsi ati ti Yoruba pẹlu. Şile meji ti ẹ ma fi ra a na, ki Ọlọrun ma jẹ ki o wọn nyin! A si tanmọ wipe gbogbo enia, ati ọrẹ, ati ọta, ati Oyinbo, ati Enia Dudu ni yio gbadun Iwe na ani Iwe Igbesi-aiye Makọli, lati ọwọ Atari-Ajanaku ọkọnrin papa!!

---

## Thanks for Sympathy.

E. Abiọdun Sogunro on behalf of the famlies begs leave to return thanks to all those who have sympathised with them by personal calls telegrams, letters, and otherwise on the loss sustaind by the death of thier loved brother Mr. Claudius Adenekan Johnson, on the 21st. of April, 1925, at his residence 49 Massey Street, Lagos.

---


## TO LET OR LEASE.

All that piece or parcel of land with the buildings thereon situate at 106, Denton Street, Oyingbo Market, Ebute Mẹta.

Apply to the EDITOR.



## White's Golden Male Tonic

(DOUBLE-STRENGTH)

Whenever a woman has not been in the family way for a long time, the fault is usually set down to some disease or other in her generative organs.

Now while it is true that many women suffer from disease yet many times the fault lies with the man, owing to weakness or some other disease of the male organs of generation. *White's Golden Male Tonic* (Double-Strength) is calculated to give full vigour to the man, and to remove all diseases which prevent breeding. Every sensible man ought to use two bottles every month, to cure or prevent weakness of the generative organs

**Made and sold only by VICTOR WHITE, Esq.**

*The Reliable Dispensary, 41 Offin Road, Lagos.*

N.B. NOT OBTAINABLE ELSEWHERE

SHAKE THE BOTTLE

## ARẸMỌ FUN ỌKỌNRIN

Nigbati obinrin ko ba tete loyun, a ma nro pe ara obinrin na nikan ni arun wa. Şugbọn nigba pupọ ni o njẹ pe ara ọkunrin ni arun wa. Egbogi yi dara pupọ fun Arẹ, Ẹda ati gbogbo Arun ti ki jẹ ki ọkunrin şe abiamọ.

N.B.—O yẹ ki gbogbo ọkọnrin ma lo igo mejimeji loşoşu—Işẹ ti egbogi na nşe ni ara ko şe royin.

Price ten shillings (10/- per bottle).


## *In Memoriam.*

In ever loving memory of my dear beloved father

DR. MỌJỌLA AGBEBI,

who departed this life on May 24, 1917.

*Thy grave shall always be kept green.*

'Tis not to conflict now,
The sound of strife is o'er,
All tears are wiped away,
And sighs are heard no more.

T'is to the Banquet spread,
To join the festal throng,
Theirs is the shout of praise,
Theirs the eternal song.

The victors crown they wear,
Crowned is their Living Head,
The wealth of heaven is theirs,
His glory on them shed.

R.I.P.

By his daughter,
LAYINKA.

**EKO AKETE**

EKO, SATURDAY, MAY 16, 1925.

## KA GA A, KA GO O, EDE NI KO YE'DE.

Loju ęgbà aimọye enia, bi igbati ęnikan da epo *petrol* si'na ti o si gbojikan fun jijo bulabula ni "Eko Akete" to jade ni ọsę to kọja ri; kete ti Iwe-irohin wa jade ni a ri ọgọrọ ninu awọn ọrę ati ojulumọ wa ti nbere pe "pa-ntiwa" bi ede Ęyọ; pupọ ni awọn ti ko duro gb'ẹjọ tilę "fi ãke kọ'ri" wa ba wa lati wa mọ idi ọrọ pataki (*Leader*) ti a kọ sinu Iwe-irohin na; bęni awọn alaimọkan miran nsọ eyi to ba wọn lẹnu mu pe, "A! "Eko Akete" ti gbęiyę" a ko mọ bi ęiyę aję ni—"Șiọ! "Eko Akete" ti gbowo ję lọdọ lagbaja" ohun ti Okete nję lo sa fi nlọ ęgbe rę, ati irufę ọrọ bę; nigbati a si gbọ pe awọn kan nsọ pe a npa ęlędę ta! ęrin la busi.

A ki batun bęrę ọrọ-ikasi ti ọsę to kọja ni mimu sọ lọsę yi mọ șugbọn fun anfani, ifọkanbalę, ati oye awọn ọrę wa wọnyi, a o gbidanwo lati tubọ la alaye ọrọ na eyiti a ri dajudaju pe o mi igboro titi.

Ewu gbigbọ tabi kika ọrọ tabi riro ero kò to ewu șișì-ęni-gbọ tabi riro ọrọ ęni si a-rọsodì ati gbigbọ ọrọ sodi pẹlu; ti ęniti a si gbọ ọrọ rę sodi na ko ba mura gidigidi lati la idi abajọ na yekeyeke fun awọn to și i gbọ bayi, o le da ọta apapandodo silę fun ọjọ gbọrọ; nitori eyi ni a șe tun sọ si ọrọ pataki na (*Leader*) gęgębi a ti wi nișiwaju.

Ki a ma ba ọrọ bọ.

### ORI-KUNKUN GOMINA SIR HUGH CLIFFORD SI ỌRỌ ELEKO OBA WA.

A gbà pe o yę, o si tọ ki a lo ede ti yio mu eti Gomina mejeji ho gẽ bi Olokun fun iwa-iwarùnkì, iwa-ainani-ęni, iwa-fifęfõ iwa-igberaga, igberaşanlę ti o hu si wa nibi nipasę orișirisi ọná-ębę ti a bę ni ti ọrọ OLOWO ti o kọ a-wigbọ-s'ęsu ti o kọ eti-gbọnin s'ębọ. Laisi ani-ani, ęnyin ọkawe wa yio jẹri si gasikia yi pe gbogbo Iwe-irohin ojugba wa lo sọ wabiwọsi tabi ba-nsa ọrọ fun Gomina nitori iwa aimọ-Ọlọrun yi, ju awa papa lọ.

### KILO MU SABABI WA PẸLU *LAGOS WEEKLY RECORD* WA?

Ori're die kọ ni Ilu Eko ni fun bibęwo ti Edward Arẹmọ Ọba King wa bę wa wo nibi ni oșu to kọja; loju wa, Gomina tabi Ijọba ibi ni ero pe boya gęgę bi inu ilu ko ti sun pętę rara nipasę ọrọ Olori wa ni Iga Idunganran, ọrọ ti Gomina parọ lati ọjọ jọjọ yi, enia ko ni pọ dabi alara lati yę Arẹmọ na si; a si ro pe eyi lo mu ki Ijọba tę awọn iwe benbe-benbe lọ janręrę ni ede wa ti nwọn si nfọn kakiri ilu fun ãjo ki ilu lo pade rę botitọ-botiyę; șugbọn laisi iwe wọnyi, awa mọ gbangba pe awọn enia wa l'Eko tabi nibi gbogbo ko ni șai șe gudugudu meje si irufę ipade bę, nitoripe awọn enia wa ko ję taro ifọn ki nwọn ho'ra de egun, tabi ki nwọn yaro ęșę Èbó lara Taiwo; ęnikęni mọ pe ilu ko ni gbọn-mi-si omi-ko-to si Arẹmọ, bikoșe si Gomina Clifford na, irufę iyęsi ti gbogbo Eko fun Arẹmọ na lọjọ *Wednesday* ọjọ kędogun oșu to kọja yi pa bambari kosi si iyęsi ti awọn enia fun n'ilu miran ti o to tiwa lọjọ to gunlę gan; gęgę bi Arẹmọ na ti jẹri si; a ko șęșę tun ma sọ bi inu Gomina ti dun to, tobę ti o fi kọwe kan sọwọ fun titę sinu Iwe-irohin Alada-nla kan ti a npe ni *Times* ni Ilu Ọba.

Nigbati Gomina si fi ma lọ patapata, ọwọ ni *Friday* ọsę to kọja, ko ha niye ninu awọn ilu to sin i, pẹlu awọn ti apakeji laika awọn ęlomiran t'Oyinbo t'Enia Dudu? Igbagbọ wa ni pe nigbati Gomina na ri pe ęnyin ilu ko doju ti on ni gbigba Arẹmọ Ọba t'ọwọ-t'ęsę pẹlu iyęsi ailef'ęnusọ ti Gomina papa ko nireti lai-fãbada, nitori ohun tian-tian—eyini ọrọ Eleko to dabi ọgbę ti ko jina lọkan gbogbo wa, tani le mọ Iwe-așiri (*Confidential Note*) ti o le kọ silę fun rere nipasę ọrọ Eleko de ęniti yio wa rọpo rę nibi? Tabi talo le sọ ohun le șe ni ọdọ Ọba King—ęniti a gbọ pe on lo ti

ękun ọrọ Eleko wa na—nigbati o ba de ... fun atunșe ọrọ na, eyini ni pe talo ... mọ bi Gomina yi nfẹ șe ore nlanla yi ... ilu ni a-șelọ bi gbunrin aditu (*Surprise* ...) lati fi rẹ wa l'ękun n'ikẹhin ati ... lati fi san ore yiyẹsi ti gbogbo wa ... owọ jọ șe laiso pe ija wa ngba wa ... lati pade Arẹmọ Ọba King na? Njẹ Gomina ba ti ni ero yi lọkan bayi șiwaju ... Iwe-gadagbagadagba kede *Record* ti o ... l'ọsẹ to kọja na, ero wo ni ẹ ro pe ... Gomina tun le ni ni ọkan lẹhin irufẹ ikede ... o? A fi idahun na le ẹnyin ọrẹ wa lọwọ; ... ti nla a yi boya awọn kan le sọ pe a ti șe ...? Idahun wa si irufẹ ẹni bẹ ni pe ... nigbati enia ba ro pe o tan fun on nigbana ... iranlọwọ Olodumare kusidẹdẹ (*Man's extremity is always God's opportunity*). Ẹnyin Onigbagbọ yio ranti itan Elijah bi ... tọrọ iku laginju njọkinni nigbati obin-binrin-atẹhintọ ndamu rẹ, ẹnyin Musulumi, yio si șe iranti itan Anabi Yesufu ... nu kanga ti ọbakan rẹ ti si.

Bẹ awa na lo ma npowe pe "a ki fi wadu-wadu la'bẹ gbigbona," tabi ja ida ... iko, njẹ bawo ni iba ti dara to ti a ba ... ki ti'nu gbe'nu, ki t'ode gbe ode, bi ... o ge ọkun jẹ pùrú, pāpā ni akoko yi; ... ẹnikẹni ma tun și wa gbo o; a ko sọ pe ... a mașe sọrọ gbun Gomina Clifford rara ... nigbati a ba nșiro ișẹ iriju rẹ, șugbọn a le ... eyi lalai jẹ ki enia fura pe a mba on ... papa jawura iwa-oșonu ati iwa-arankan ...

A șebi ohun ti a ba nwa lo ngbọn ju ni lọ? Ẹnyin ara-ibi na ko niran imọran towọ ti Alagba wa kan Oni-șokoto gbọrọ gba awọn Janma Musulumi nigbati ẹjọ Mọșalași wọn și șe fikanfikan nijelo? Bi Alagba na ti damọran fun wọn pe ti nwọn ba fẹ ki ọwọ wọn tẹ ohun ti nwọn nfẹ—eyini ni Mọșalași Jimọ, ki nwọn pada lọ kirun lẹhin Lemọmu Braimah; șe a ri ọgọrọ awọn alaironu-jinlẹ niran nigbana ti nwọn bẹrẹ si sọ ọrọkọrọ si alagba wa yi lara, "A, o ti lọ gbowo lọwọ wọn o! A, o ti yi o," ni diẹ ninu ọrọ ti nwọn nsọ si alagba Ọgbẹni wa lara lasiko na: nigbati awọn Janma Musulumi si fi ẹjẹ sinu ti nwọn tutọ funfun jade nkọ, talo jori ẹnikan loni? Njẹ, ki a sọpe awọn agbagba ninu awọn Musulnmi na kigbe nigbana bayi pe "Hẹn nibo ni ago mbọ! ki awa tun pada lọ kirun lẹhin ẹniti a ti yọ ti Iwe-irohin wa *Times of Nigeria* ti tẹ yiyọ rẹ fun gbogbo aiye ka lẹkan ri! Oti o, bo-ti-mari-lomari" !!! njẹ, ọwọ awọn Janma Musulumi le tẹ Eka Ida loni baun? Awọn Ebo lo ma npowe pe *A patient dog eats the fattest bone*, eyini nipe "Aja to ba mu suru ni iri mudunmudun-atata la!"

Njẹ awọn to ba ni binu Iwe-irohin ọsẹ tokọja ha ti i bere idi rẹ ti awọn Ogunna gbongbo ninu awọn Janma Musulumi fi sin Gomina Clifford lọjọ *Friday* tokọja bi? A bi a ha le sọ pe awọn ilu tun yi biri bi Agogo bi? Kamari! Kamari!!

Ẹnyin enia wa, bi ọrọ na ti ri nũ, a ko jẹ fi igbakan wa ibi ilu wa yi, tabi awọn ti a mọ pe nwọn nșișẹ ilọsiwaju rẹ lọju mejeji *lainireti ere kan* lati ọdọ ẹnikẹni, bikoșe Ore-ọfẹ lati oke wa.

A si fẹ ki ẹ mọ dajudaju nigba gbogbo pe:—

Bi ilu ba da si meji,
T'Ọba la ma ã șe.

---

## IWE IYẸSI TI NWỌN NI ILU FUN AREMỌ ỌBA.

[*Lati ọwọ* ATARI-AJANAKU.]

Si Oni'we-irohin "EKO AKETE."

Mo bẹrẹ f'oji,

Ni ede Oyinbo ni a șe wosika wa ti ọsẹ ti o kọja, nipasẹ Iwe-iyẹsi ti awọn melo kan fifun Arẹmọ-ọba ni orukọ gbogbo ilu; ănu si șe wa pupọ wipe Oni'we-irohin wa ko tẹ gbogbo rẹ tan lẹkan, o ni, iyoku di ọsẹ yi: ti o ba tẹ ẹ, ẹ o ri i ka ni oke iwe yi pẹlu ọrọ diẹ ti a sọ nipasẹ Gomina Ọlọla *Sir* Hugh Clifford; bi bẹ kọ, iyoku ku si ọwọ Ọgbẹni Oni'we-irohin wa.

Bi a ti șe așaro lori Iwe-iyẹsi yi ni ede Gẹsi, a ki ba ti gb'ẹnu le ọrọ kanna ni sisọ mọ ni ede Yoruba, bikoșe bi o ti jẹ ọrọ pataki to, ani, ọrọ ti a ni lati fi yé gbogbo ilu yekeyeke.

Wipe Arẹmọ-ọba wa bẹ wa wo ni oșu ti o kọja ni ilẹ yi, tabi-tabi ko si ninu eyini, bẹni o si daju wipe inu gbogbo wa ni o dun si wiwá rẹ. Ko si

ohun iyẹsi kan ti a le ṣe fun Arẹmọ-ọba na li ọna ti o tọ, ti o le pọju, bẹni ko si si ẹbùnk'ẹbùn ti a le fun u, ti o le pọju. Ṣugbọn iyẹsi wo ni Ijọba jẹ ki awọn ara Eko ṣe fun u, tabi ẹbùn wo ni nwọn fi ta a l'ọrẹ ?

Nitotọ, ilú yẹ Arẹmọ-ọba si, ati ẹniti Ijọba fi iwe pè, ati ẹniti nwọn ko fi iwe pe, t'ọkunrin, t'obirin, t'ọmọde, t'agba ni o ṣe aṣeyẹ fun Arẹmọ-ọba ni ọjọ ti o wọ ilu, fun gbogbo akoko ti o fi wa ni ilu, ati titi o si fi kuro ni ilu pẹlu alafia ati ara lile.

Iyẹsi ati aṣeyẹ wọnyi dara nitotọ, ṣugbọn ki a wipe ọwọ ilu papa ni èto iyẹsi wa ; ki a wipe Ijọba fi aye fun ilu lati tẹ ifẹ wọn l'ọrun nipasẹ iyẹsi yi, bawo ni iba ti dun to ? Ọpọlọpọ eré ni a ba ṣe fun Arẹmọ-ọba, eyiti a ko ri aye ṣe : ọpọlọpọ nkan pataki ni a ba si ṣe si ilu, ti a ba ma fi ranti didé Arẹmọ-ọba lai ati lailai ; gẹgẹ bi apẹrẹ, a le da owo ti a ba ma fi kọ bi Kiriyo mẹrin, Musulumi mẹrin ni iwe ọfẹ, ni ọdọdun, ni Ṣukuru giga *( Secondary Schools, )* iba si tun ni anfani ipese miran ti a ba si ma ṣe fun "ko bere, ko bere" mẹrin-mẹrin ni ọdọdun pẹlu. Eyi jẹ kekere ninu pataki, pataki, ti ilu iba ṣe ni iranti ibẹwo ti Arẹmọ-ọba bẹ wa wo ; ṣugbọn, bi ilu ti nṣe ipalẹmọ bayi, bẹni awọn ọmọ-lẹhin Dokita Randle si bẹrẹ si ṣe tiwọn, ninu eyiti ko si eto kan pataki ti o wu ni lori, ju "Wi Kọnkọ̀" *( We concur )* pẹlu etok'eto ti Ijọba ba ṣe.

Ti o ba ṣe wipe Ọlọla Ọgbẹni Kitoyi Ajasa ni o gbe iwe ti Ọlọla Ọgbẹni S. H. Pearse gbe jade ni, fun Ipade ni Ile-ẹgbẹ, lati ṣe aṣaro ẹyẹ ti o tọ fun Arẹmọ-ọba ni Eko, boya iba tilẹ san diẹ.

Nitori (ki a tilẹ sọ wipe) a ko mọ ilu ti Ijọba fi *Lawyer* Ajasa ṣe aṣoju rẹ ni Igbimọ *Legislative Council*, ilu, tabi ibiti Ijọba npe ni *Colony Division* gān, bi Ajiran ni, tabi Oworonṣoki, tabi Igboṣere, nibiti nwọn ti nko Ẹja Ṣawa ati Efolo wa, a mọ̀ wipe ilu mẹtẹta wọnyi, iyẹn ti o ba tilẹ jẹ aṣoju ibẹ ni Lọya Ajasa nṣe ; ani, ilu mẹtẹta wonyi ko jina si Eko pupọ, ninu Eko yi kanna ni ki a sa sọ wipe nwọn wa ; ṣugbọn, atari-ajanaku ni, ki nṣe ẹru Ọlọla Ọgbẹni S. H. Pearse ti oke Olowogbowo, Aṣoju Ẹgba Abẹokuta, lati gbe Iwe-eto bi a o ti ṣe ni Eko si ode, ti o fi Ake silẹ, tabi ki o lọ gun ori oke Olumọ lati ba awọn Ẹgba j'iroro, bi nwọn yio ti ṣe aṣeyẹ tiwọn li ọhun si ; ti o si pe Ipade, ti enia mejila, tabi enia mẹtala lọ, ni Ile-ẹgbẹ li Ẹhingbẹti, l'ai ba Ọlọla Lọya Shyngle, Lọya Moore ati Dokita Jones, awọn Aṣoju Eko sọ ọ tẹlẹ, bikoṣe iwe lasan ti o fi ranṣẹ si wọn nigbana wipe ki nwọn wa si Ipade, eyiti nwọn fi Dokita Randle ṣe Olori, Alakoso ati Alaga rẹ. Iwọsi, Ọkọ-èro !

L'aiṣe wahala kan mọ lati hú oku ọrọ silẹ, èto ti ilu ṣe ati Igbimọ ti nwọn yàn, *Lieutenant Colonel* Moorhouse ni ko dara, eyiti awọn Dokita Randle, Ọbasa, Lọya Ajasa ati awọn Ọmọ-ẹgbẹ wọn yoku si yan ni ile *Colonel* Moorhouse, Gomina sọ ọ d oku. Eyiti Gomina papa si tun yan, Oyinbo ni pọju nibẹ ; Yanmurangi jo, ko jo 're, Yanmurang gbe e l'ẹsẹ : Gomina gbe aja ta, o fi ra ọbọ !

*Colonel* Moorhouse da nkan rú tan, o ko si Ọko o mu ọna ilu rẹ pọ̀n ; (ṣugbọn, a-lọ ramirami ni nri, a ko nri àbọ rẹ !) Waya si ti de si ọwọ wa ni ọsẹ ti o kọja lati Ilu Oyinbo wipe, *Colonel* Moorhouse ko tun ni fi ẹsẹ rẹ tẹ Eko yi mọ !

Lẹhin ti Gomina ti yan Igbimọ tirẹ fun iyẹsi Arẹmọ-ọba tan, ilu birẹhin pẹlu ipinnu wipe abuku-k'abuku ti o wu ki ẹnikẹni le ta fun wọn nipasẹ ọrọ ti Arẹmọ-ọba yi, ki yio di wọn lọwọ rara lati bu ọla fun Arẹmọ-ọba na, bẹni ki yio si di wọn lọwọ, ẹwẹ, lati ṣe aṣeyẹ ati iyẹsi fun u, be gẹgẹ ni nwọn si ṣe. ***Alhamdu Lilahi !***

Ki a lọ pade Arẹmọ-ọba, ki a ma jo, ki a ma yọ iyẹsi kanni nitotọ, ṣugbọn ti a ba kọ ọrọ iyẹsi na si iwe, iyẹn ni Arẹmọ-ọba yio ri mu lọ s'ile : papa lati fihan baba rẹ, ayanfẹ Ọba wa. Nitorina, iwe pataki ni eyi ni lati jẹ, enia pataki li o ni lati fi ọwọ sinu rẹ, nwọn si ni lati ṣe Ipade Gbogbo-gbò ki nwọn gba aṣẹ ilu ki nwọn to le fi iwe na ranṣẹ bi bẹ kọ, akọ yẹyẹ ni nwọn nṣe, ohunkohun ti nwọn ba si sọ sinu iwe na, ninu apo ara wọn ni nwọn sọ ọ si.

Ki a tilẹ wipe enia tẹ ṣe iwe aramu tabi iwe arumọjẹ, ni orukọ ilu, l'ai ba ilu sọ ohunkohun tẹlẹ nipa rẹ, ti o ba ṣe adabọwọ irufẹ iwe bẹ tan, ko ni lati gbe e fun enia atata kan, ki a ma ṣeṣe sọ ẹni nla, ati ẹni ọlá, bi Arẹmọ-ọba *( Prince of Wales. )*

Anu ṣe wa pupọ lati sọ wipe iwe arumọjẹ ti nwọn gbe fun Arẹmọ-ọba lọ, niwọn bi o ti jẹ wipe nwọn ṣe e ni orukọ ilu, l'ai ba ilu sọ ohunkohun ati l'ai gba aṣẹ ilu. Ati Oyinbo, ati Enia Dudu, mẹrindi-ladọta pere ni gbogbo awọn ti o fi ọwọ si iwe na, ẹlomiran ninu wọn ni o si fi ọwọ si iwe na pẹlu ibẹru wipe boya, ti on ba kọ̀ lati fi ọwọ si i, o le di ijọngbọn si on l'ọrun ; ẹlomiran si fi ọwọ si i nitori o ro wipe gbogbo ilu li o ni ọwọ ninu rẹ ; awa si tanma wipe eyi ni o jẹ ki a ti ọpọlọpọ orukọ ti a ko ni ireti lati ri ninu iwe arumọjẹ bayi nibẹ.

Ki a tilẹ wipe awọn ẹni mẹrindi-ladọta ti o fi ọwọ si iwe na pe nwọn fi ọwọ si i, nitori ara wọn, iyekan, ọbakan, ati gbogbo ẹbi wọn ; sibẹsibẹ, o le di ijọngbọn si wọn l'ọrun, nitori l'ai ba gbogbo ẹbi sọ ọ tẹlẹ, ẹbi miran le wipe adabọwọ iṣẹ ara wọn ni nwọn jẹ, awọn ko ran wọn niṣẹ ; melomelo nigbana ni o yẹ ki a tako wọn, nigbati nwọn ba lo orukọ gbogbo ilu fun nkankan l'ai gba aṣẹ ilu, lai ba ilu sọ ọ tẹlẹ. Njẹ nitorina, a bere, o yẹ ki a wijọ nisisiyi, tabi ko yẹ ? Ẹ dakẹ ni ? Ẹ dahun ! O dabi ẹni wipe mo ngbọ idahun nyin nisisiyi wipe, O yẹ bẹ !

L'aiṣẹ, l'airo, Gomina Ọlọla Hugh Clifford fi abuku kan Eleko ni ọdun karun : ẹniti o ba si sọ wipe Eleko ṣẹ, ki oluwa rẹ sọ ohun ti o ṣe !

...koli ti o sọ ọrọ Eleko ni Ilu Oyinbo, ti o si ti ...eyiti o ju bẹ lọ ni ilẹ yi nipasẹ Eleko, ti ohun-...ko si ti idi rẹ yọ; eyiti o sọ ni Ilu Oyinbo, ...sọ wipe Eleko ni o ran on, bẹni Eleko papa ko ...sọ wipe on ni o bẹ Makọli l'ọwẹ: Makọli ti o si ...ọrọ wọnyi kọ iwe wipe, eyiti on ba fi purọ ninu ...tabi eyiti on ba şi sọ, ki Ijọba tabi Gomina ...fowo on, lati igbati Makọli si ti de lati Ilu ...inbo, titi Gomina papa fi ko si Ọkọ ni ijẹsan, ...le gb'oju-gb'aiya bere lọwọ Makọli. A wi ...wayi o, nwọn ni ki Eleko wa lu agogo; bi ...ogo gbanjo ni o, awa ko mọ! Ti o ba tilẹ jẹ ...ọrọ ti Makọli sọ sinu iwe ni Ilu Oyinbo gãn ...Ijọba ni ki Eleko lu agogo nipa rẹ ni, iba san ...; şugbọn, ọrọ ti Makọli ko sọ, ni Gomina fi si ...Eko l'ẹnu, ti o si ni ki o lu agogo nipa rẹ! ...omiran sọ wipe, Ọpa Eleko ti Makọli mu dani ...bi Sẹkitẹri Oloye Oluwa, ni o bi Gomina ...: ewo ni àbọrọ bi Gomina ninu, ninu ẹyini: ...ni Makọli fi kọ iwe si Iwe-irohin Ilu Oyinbo ...Kalamu? Ki a tilẹ sọ wipe Ọpa ni o fi kọ ọ, ...ni o kan Gomina ninu rẹ? O ha mọ igbati ...Victoria fi Ọpa na ta Dosumu Ọba wa lọrẹ ...apẹrẹ ati majẹmu ọrẹ?

...Nigbati Ọba Dosumu ngba ẹgbẹrun pọnwun ...odun lọwọ Ijọba ni 1861, ẹdẹgbẹta pọnwun pere ...Gomina Eko ngba l'ọdun nigbana!

...Nitori ọrọ agogo yi ni Gomina şe da Eleko ...ro, eyi si jẹ ọrọ ibanujẹ fun ilu; nitorina, ilu kọ ...-ẹbẹ si Gomina, ẹdẹgbasan ati ẹgbẹrun ọna ...ẹtadi-logun enia ni o fi ọwọ si Iwe-ẹbẹ na. Ninu ...obakungbe èsi ti Gomina fi si iwe na ni o sọ wipe ...gbẹrun ọna mẹtadi-logun enia ko to rara lati fi ...ọwọ si Iwe-ẹbẹ li orukọ gbogbo ilu! Tani tun le ...nigbana pe Gomina ti o sọ wipe ẹdẹgbasan ...kere pupọ ju lati şe oju ilu, le tun la oju rẹ ...ejiji silẹ, ki o si jẹ ọhẹn si Iwe-iyẹsi ti enia ...ẹrindi-ladọta pere sọ pe awọn kọ si Arẹmọ-ọba ...orukọ gbogbo ilu!!

...Ela l'ọrọ. A ko sọ wipe o di igbati gbogbo ilu ...fi ọwọ si Iwe-iyẹsi ti Arẹmọ-ọba, ki a to le fi ...iwe na ranşẹ l'orukọ gbogbo ilu, agbẹdọ! Şugbọn ...tun ti a nsọ ni wipe, bi o tilẹ şe enia kan şoşo ...ere ni yio fi ọwọ si Iwe na li orukọ gbogbo ilu, ...buru, bi Ipade ilu Gbogbo-gbõ ba ti fi aşẹ si i, ...bọn Iwe ti o şe wipe lati ile Balẹ ilu *(Resident of the Colony's quarters)* ni nwọn ti nranşẹ pe enia ...ti nwọn fẹ, tabi ti nwọn mọ, tabi ro wipe yio ...ọwọ si i lati wa fi ọwọ si i,

ARUMỌJE IWE NI!

...Iba şe kiki ẹbi pe Ilu ko mọ ohunkohun nipasẹ ...arumọjẹ ti nwọn fun Arẹmọ-ọba ni awọn to ...iwe na jẹ ni, boya iba san diẹ; şugbọn nwọn ...jẹbi aidara ọrọ mọşaşi, sondo'ko, ti nwọn sọ ...Eko lara wipe lati ọjọ ti iwa şẹ l'Eko, titi ...ọjọ ti Ijọba ta asia Gẹsi s'ilẹ yi ni ọdun kẹrin-...logota ọhun, *(64 years ago)* ko si ẹnikẹni to mọ ohunkohun ti o njẹ ofin, ati eto ni Eko, ogede omugọ ati Keferi lo kun gbogbo Eko, iwa jandukun, iwa ara oko ni gbogbo Ilu nbu, ninu ewu nla ni ẹmi gbogbo enia wa, işekuşe ni awọn oloye njẹ ki enia şe owo, okuru iyẹpẹ ati irá tabi amọ ilẹ amijẹjẹ ni Eko, ati pe Eko si ni olu ilu ti owo ẹru wa.

Bayi ni nkan ha ri ni Eko nitotọ ni ọdun kẹrin-lelọgọta nitosi nbi? Bi bẹni, bi bẹkọ, ao jẹ ki ẹ mọ l'ọsẹ to nbo lagbara Baba.

Emi ni ti nyin nitotọ,

ATARI AJANAKU.

---

### *THE EDITOR'S OBSERVATORY.*

#### Matthew the Publican, softly, softly!!!

Disquieting news reach us of the high-handed policy which is said to be the order of the day, in the matter of tax-gathering at Ilaro: pleople who come from other towns or villages for marketing in this place, to say nothing of perfect strangers with perhaps 24 hours' sojourn therein, it is alleged, are generally pounced upon almost in cat-and-mouse fashion, to pay tax without the least pains to enquire whether or not these have already contributed their own quota to the fund at the places from which they come, with the result that the Ilaro-five-day market which usually always was full to over-flowing before, is not now dwindling in the number of attendance and in the supply of foodstuffs etc. for sale.

If the staggering news is true, and we have no reason to doubt the source of our information, the sooner the D.O. in charge of the district investigates and checks this apparently growing evil, the better will be for those thus adversely affected.

#### Unitarian Christian Church to the fore!

From and after Sunday the 24th instant, (Empire Sunday) Divine Services will be held in connexion with the above Church, at Arapa Hall (temporarily) 21, Williams Street, Lagos, opposite *Eko Akete* Offices, as follows:—

Morning 10 a.m. (Yoruba Sermon)
Evening 6.30 p.m. (English Sermon)

All are welcome.

#### Nigeria's First Minister of State.

The Honourable The Chief Secretary to the Government, Frank Morrish Baddeley was sworn in as the Officer administering the government of Nigeria by His Honour Sir Ralph Combe, C.J. in the Council Chamber at 4.20 p.m. on Friday the 8th instant amdist quite a representative gathering. After the ceremony His Honour reviewed the Fourth Detachment of the Nigerian Regiment amidst the booming of guns.

God save the King!

#### Farewell, Nigeria!

*Nigeria Gazette (Extraordinary)* to hand this week contained the Governor's Valedictory Address to the members of the Public Service, Missionary bodies and European Merchants, etc.

#### The Kapo Case.

Judgment was reserved in the above case in the Assize Court yesterday.

Barrister E. J. Alex Taylor for the accused we learn, addressed the Court at some length.

## BANUSỌ.

Ma jẹ k'ero ọla
Fi 'banujẹ fun ọ,
Iṣẹ ta yan ọ si,
Ṣe e laṣegbadun,
B'ero kun okan tẹ,
Maṣe ro jinna ;
B'ọkan otitọ rẹ,
Yio fọ ọ s'ọna.

Tani oluwa rẹ,
To m'eni m'ọla ?
Ọkan to wa ninu,
Amọna kan ni ;
Ohunkohun to de,
Tab'eyi ti mbọ,
D'opo otitọ mu,
Yio f'ọna han.

Kiṣẹ gbogbo ọrọ
Lo yẹ ka fun ka ;
Omiran wa to yẹ
Ka ba inu sọ.
Nnu 'po wa l'aiye yi,
Ki lo tọ to yẹ ?
Bi ki inu wa mọ,
K'ero mọ pẹlu.

Ẹru rẹ yio fuyẹ,
Ẹni banusọ ;
On ki yio si ṣina
Lọsan tabi'oru.
Ọkan titọ, pipe
Ti ntọ ni sọna,
Ki ba le jẹ temi,
Nki yio ṣina mọ.

AFỌLABI JOHNSON.

## IN MEMORIAM.

In loving memory of my dear brother
VICTOR ANNIE JOSEPH EUBA,
who died at Ikirun, on the 13th day of May, 1913.

"Nineteen-thirteen ! What a year it has been
Whilst alive I will never forget it
As now I feel, I say, and I mean
I wish, I had never met it."

"*Requiescat in Pace*"

E. CORNELIUS WICKLIFFE.

22, Allen Street,
Ebute Metta,
Nigeria.

## Notice.

THE NATIONAL CONGRESS OF BRITISH WEST AFRICA.

THIRD SESSION.

The Third Session of the National Congress of British West Africa which was fixed to take place at Bathurst, Gambia, this month has been postponed until further notice.

E. AKIOLA FRANKLIN
A. LATUNDE JOHNSON
*Joint Secretaries, Lagos Branch.*

OLORI JU OLORI LỌ, OLORI JU OLORI LỌ OLORI BAGANDOJI

Irohin kekere ko lo kan wa fun Ere ti awọn Ẹgbẹ Sodẹ ṣe ni 81 Johnson Street, Tọlọ ni ojude Olori awọn Atiku Silva Pedro ni *Saturday* Ijẹjọ; agba fun awọn Ẹgbẹ na, aṣọ aran npẹ aṣọ ran ranṣẹ nibẹ. Balogun to pe ni Balogun Olori to pe ni Olori ni jọna. A ṣe yi ṣa mọdun o, Aṣẹ. Olori Sodẹ mo gba fun nyin o.

AWODIOKE.

## IN MEMORIAM.

In loving memory of our dear Uncle
DISU ỌDẸDINA ADETUTU
who departed this life at Igbobi on the 7th May 1920.
Uncle dear, rest in peace.

M. A. ỌDUNJO,
S. A. ỌYADINA.

In affectionate remembrance of my dear father
GEORGE ALFRED WILLIAMS
(*Late Editor of the "Lagos Standard."*)
Who departed this life on Sunday, the 18th day of May, 1919.

"So part we sadly in this troublous world
To meet with joy in sweet Jerusalem."

HIS DAUGHTER, EVA.

"O di ọdun marundi-logoji nisinsinyi ti a ti bẹrẹ si ṣe *Mentholatum*, a si mọ ọ kakiri gbogbo aiye bi egbogi ti o wulo fun wiwo:—Otutu oriṣiriṣi, Ọna-ọfun ti o ndun-ni, Ori-fifọ, Arun Awọ-ori, ati gbogbo Arun Awọ-ara."

---

Mentholatum has been manufactured for 35 years and is known throughout the world as a medicine of great value for Colds, Sore Throat, Headache, Scalp Troubles and all skin ailments.




A HEALING CREAM
**Mentholatum**

## Preachers for To-morrow.

AWỌN ONIWASU ỌLA.

ROMAN CATHOLIC. (HOLY CROSS)

Masses will be sung by Priests appointed. Awọn Paddi ti a yan yio ṣe Isin ni gbogbo ẹkọko wonyi.

( MORNING )

Masses Isin Arọ,

6.30 7.30 8.30 9.30
7.30 8.30 9.30 10.30.

( EVENING.)

(Benediction) Isin Ibukun.

4.45—5.30. 6.45—7.30.

ST. MICHAEL'S ) Lafiaji.)

MORNING. 7—8 8.30—9.30
EVENING. 5.45—6.30

ANGLICAN

Time. Preacher.
9 a.m. Christ Church, Bishop of Lagos
6.30 p.m. do. Rev. J. H. Ogunro
9 a.m. St. Paul's ( Breadfruit ) Bishop I. Oluwọle
6.30 p.m. do. The Curate
9 a.m. St. John's ( Aroloya) Rev. H. V. E. Johnson
6.30 p.m. do. do.
9 a.m. & 630 p.m. St. Peter's (Alapako) Rev. S. V. Latunde
9 a.m. & 6.30 p.m. Holy Trinity (Ebute-Ero) Rev. S. J. Gansallo
9 a.m. St. David's (Jordan) Rev. J. H. Ogunro
6.30 p.m. do.

WESLEYAN

10.30 a.m. Tinubu Rev. L. R. Potts-Johnson
7 p.m. do. do.
10.30 a.m. Ereko Rev. A. N .Cole
7 p.m. do. Rev D. A. Tekoe
10.30 a.m. Olowogbowo Rev. E. E. Williams
7 p.m. do. Rev. A. N. Cole
10.30 a.m. Ọbun Eko Rev. S. A. Pearce
7 p.m. do Bro. C. W. Faulkner-Shaw

AFRICAN

9 a.m. Jehovah Shalom Bro. Ayọ Ajala
7 p.m. do. Bro. Ọlaboye Laleyẹ
9 a.m. Christ Church ( Ebute Mẹta ) Bro. Bro. W. K. Fafunwa
6 p.m. do. Rev. J. F. Ogunko
9 a.m. Bethel Bro. A. Abọyade Cole
7.30 p.m do. Rev. J. Ṣotayọ Williams
9 a.m. Zion
6.30 p.m. do.
9 a.m Salem Church ( Ebute Mẹta ) Rev. E. David-Ṣodẹinde
6.30 p.m. do. Bro. M. T. Akinsọwọn
9 a.m. Bethlehem Church ( Ebute Mẹta ) Rev. J. A. Wright
dọ. Bro. J. E. Ṣowọnọla
Williams' Memorial ( Wesleyan ) Ebute Mẹta
10.30. a.m. Rev. D. A. Tekoe
7 p.m. Bro. J. W. Smith

10. a.m. African Methodist Bro. E. A. Amuse
7 p.m. do. Bro. J. O. Oyekunle

BAPTIST

10.30 a.m.
6.30 p.m, Rev. J. R. Williams.
9 a.m. Ebenezer Rev. E. C. Alabi
6.30 p.m. do.
9 a.m. Ararọmi Rev. A. A. Puddicombe
6 p.m. do

ISOLARIAN BROTHERHOOD

7.30 a.m. Ilupesi The Founder
7 p.m. do. Supt. A. Ibaru

St. STEPHEN'S (EPETEDO)

9 a.m. & 4 p.m. Rev. Patriarch J. G. Campbell

AHMADIA (ISLAM.)

6 a.m. Fajir Service Y. P. O. Ṣodẹinde
5.30 p.m. Open Air Service Imam K. R. Ajose ( Central Mosque, Arọloya Street.)

ZION CONGREGATIONAL

9 a.m. Kakawa St. Locum Tenens
7 p.m. do. do.

SALVATION ARMY

10 a.m. Glover Memorial Hall Capt. Jones and the cadets
7 p.m. do.

CHURCH OF GOD

10 a.m. 22 Ọdunlami Street, Breaking Bread
7.30 p.m Open Air Service at Campbell Square Wm. C. T. Terrell.

UNITARIAN

5 p.m. Exhortation Meeting ( Arapa Hall ) 21, Williams Street

AFRICAN FAITHIST KOSMON

5 p.m. 8, Shitta Street. Bro. A. Gbogbonde

---

## IGBẸ L'OWO WÀ

### EKO.

Bi òwò Ekurọ, Epo ati *Cocoa* ti kusi ọsẹ yi leyi :—

EKURỌ

£15 5 0 fun *ton* kan

EPO.

£25 fun *ton* kan

COCOA.

£28—£30 fun *ton* kan.

### KANO.

GROUND NUT.

£13 7 6—£14 fun *ton* kan

## J. C. VAUGHAN

Ti Ile-Ọja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Ọja "Excelsior" ni Ita Agarawu, ni oniruru awọn obun ... fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

O ti nṣowo Irin Işẹ lorişirişi lati adọta ọdun ... titi di oni.

ATARI AJANAKU ni ỌGBẸNI na jẹ ninu ... onişowo Irin Işẹ ni ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo pọ ọ.

## Ero ya wa ra

ADEBOYE ŞOLANKẸ Onişowo "Gbabiọgẹdẹ" nta Panu-kikọle ati kikan-ṣọ, Iṣo lorişirişi, Kọkọrọ (Işika) t'ilẹkun ati t'apoti lorişirişi, Atupa fifalọwọ, Simẹnti, Ọda lorişirişi ati Epo-ọda, Fikifiki, Okun ẹrọ, ati Ọşan, ati Pakun ti Awo-ẹja lorişirişi, Awo ti awọn Aganyin fi nko Ẹja-şawa Okun ati Ẹja Abọmafọ, ni Şọbu rẹ ni No. 4, Idunmagbo Street, (I'ebute Olowu) ati ni No. 19, Moloney Bridge Street, (I'Anikantamọ) l'Eko.

O nta Iworo (Golu) ati Fadaka-tutu ati Irin-işẹ Agbẹdẹ Iworo ati Fadaka.

Owo Ọja rẹ fanimọra. Ẹ lọ ra tiyin nibẹ

## Coffins to suit your Taste.

Coffins with Pillows, Shroud, Brass Edges, and Removable Lids, on sale at A. Kessler's Establishment, 7, Labinjo Lane, Lagos: also Gramophone Records, Gas-lamps, etc., etc.

Prices to suit you. No worry, prompt attendance. Make a call.

## Coffin! Coffin!! Coffin!!!

With excellent workmanship and finish on sale at Paul I. Samuel's Workshop 40, Campbell Street, Lagos.

Residence and Office 72 Igboşere Road Lagos.

## Ask From Kaduna Stores.

Everything for Bicycles, Motors, and Gramophones. Newly arrived Gramophones and Zonophones, at cheapest prices as follows:—

£1. 10s. od., £1. 15s. od. to £2. 0. 0.

We also stock special Louder Gramophone needles; these needles play four-records at one time.

Yoruba and English reccords of the latest amusing time.

For Particulars apply to the Manager.

S. A. CLAY

No. 79, Ọdunfa Street, or
1, Macaulay Street,
Lagos.

**Cable Address:—**
"Steinafrik" HAMBURG

## E. H. STEIN & Co.

HAMBURG, Neurwall 16/18
Hildebrandhaus
*AFRICAN MERCHANTS*

***ALL INDENTS EXECUTED.***
for
English and Continental Goods
and
PRODUCE
Sold on Best Terms.

**Produce to Europe covered by Floating Marine Insurance Policy.**
*P. O. Box No. 505.*

Agent in Lagos:—
**Mr. Karimu Kotun**
3, DOSUNMU STREET.

## Ruby Plates! Ruby Plates!! Ruby Plates!!!

BOON TO GOLDSMITHS

*Just arrived.*

Call at once and make your choice from:—

DURO THOMAS,
55, Massey Street, Lagos.

# A. Kessler,

**7, Labinjo Lane,**

**Williams Street,**

***P.O. Box 459***

Highly Recommended :

CRYSTALL LAGERBIER
LÖWENBRAUEREI HAMBURG

THE

# Pilsener Beer

*"Crystall" Brand*

*Light & Sparkling*

**Per Case**

**33s.**

**Send for a trial case to-day and convince yourself of the first quality of this Beer.**

## GBOGBONIṢE FUN OBINRIN

Egbogi yi dara pupọ fun Aboyun, ijọ, Ẹda Aran, Oyun ti o ba fẹ bajẹ ati orişirişi arun ti ki jẹ ki obinrin bimọ.

PRICE 10/- PER BOTTLE

"SHAKE THE BOTTLE."

A nta Egbogi yi ni Ṣabu Egbogi Ọgbẹni Victor White, 41, Offin Road, Lagos.

## WO'BI ẸNIKEJI,

Oniruru Posi li o wa fun tita ; lọdọ Paul I. Samuel owo wọn bẹrẹ lati Pọun meji abọ titi de Pọun mejila şile mejila. Ẹ le ri wọn ra ni 40, Campbell Street, lẹba Ile-isin Ṣọṣi Ebenezer ; ati ni No. 72, Igboşere Road, nitosi *King's College.*

## White's Convulsion-Killer.

(FOR BOTH CHILDREN AND ADULTS.)

**Sold only by VICTOR WHITE, Esq.**
**The Reliable Dispensary.**
**41, Offin Road, Lagos.**

DIRECTIONS :—For adults one Tablespoonful every halfhour until the fit is gone. As a preventive, one Tablespoonful every morning before food. For Children, one desertspoonful, in the same manner.

**"SHAKE THE BOTTLE."**

## EGBOGI AIPERI.

(Fun Ọmọde ati Agbalagba.)

Akajuwe :—Fun Agbalagba, Şibi ti a fi njẹ irẹsi meji-meji ni ababọ Wakati, titi aiperi na yio fi fi oluwa rẹ silẹ. Fun ọmọde şibi kọkan bakanna.

Ki Aiperi ma ba şeni :—Fun Agbalagba, ki a ma fi şibi meji-meji tẹlẹ inu lọrọ. Fun ọmọde şibi kọkan. Ki a mi igo na daradara ki a to mu egbogi na.

**PRICE FIVE SHILLINGS (5S) PER BOTTLE.**

When replying advertisers please mention *"Eko Akete".*


PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING PRESS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.